51

# AWỌN ARA KOLOSSE

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU, Apọsteli Jesu Kristi nipa ifẹ Ọlọrun, ati Timoteu arakunrin wa, (Ef 1:1.)

2. Si awọn eniyan mimọ́ ati awọn ará wa olootọ́ ninu Kristi ti o wà ni Kolosse: Oore-ọfẹ fun yin, ati alaafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa. (Rom 1:7.)

**Paulu nfi Ọpẹ fun Ọlọrun.**

3. Awa ndupẹ lọwọ Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, awa sì ngbadura fun yin nigba gbogbo. (Ef 1:16.)

4. Nigba ti awa gburo igbagbọ yin ninu Kristi Jesu, ati ìfẹ́ ti ẹyin ní si gbogbo awọn eniyan-mímọ́. (Ef 1:15; Gal 5:6.)

5. Nitori ìrètí ti a gbé kalẹ̀ fun yin ni ọ̀run, Nipa èyí ti ẹyin ti gbọ́ ṣáájú ninu ọrọ̀ otitọ́ ti ihinrere, (1 Tess 5:8; 1 Pet 1:4.)

6. Eyi ti o de ọdọ yin, ani bi o ti nso èso pẹlu ni gbogbo ayé ti o si npọ si i, bi o ti nṣe ninu yin pẹlu, lati ọjọ ti ẹyin ti gbọ́, ti ẹ̀yin si ti mọ oore-ọfẹ Ọlọrun lotitọ; (Matt 24:14; Jhn 15:16.)

7. Ani bi ẹ̀yin ti kọ́ lọdọ Epafra iranṣẹ ẹlẹgbẹ wa olufẹ, ẹni ti o jẹ olootọ́ iranṣẹ Kristi nipo wa, (Film 23; Kol 4,7.)

8. Ti o si ròhìn ifẹ yin ninu Ẹmi fun wa pẹlu. (Rom 15:30.)

**Adura awọn Aposteli.**

9. Nitori èyí, lati ọjọ́ ti awa ti gbọ́, awa pẹlu kò sinmi lati maa gbadura ati lati maa bẹ̀bẹ̀ fun yin pe ki ẹ̀yin lè kún fun ìmọ̀ ifẹ rẹ̀ ninu ọgbọ́n ati ìmoye gbogbo ti i ṣe ti Ẹmí; (Ef 1:15,18; Rom 12:2.)

10. Ki ẹ lè maa rìn ni yíyẹ niti Oluwa si ìwù gbogbo, ki ẹ si maa so èso ninu iṣẹ rere gbogbo, ki ẹ si maa pọsi i ninu imọ Ọlọrun; (Ef 4:1; 1 Tess 4:1; Rom 1:13.)

11. Ki a fi ipá gbogbo sọ yin di alagbara, gẹgẹ bi agbara ogo rẹ̀, sinu suuru ati ipamọra gbogbo pẹlu ayọ̀; (Ef 3:16; 4:2; A.A. 5:41.)

12. Ki a maa dupẹ lọwọ Baba, ẹni ti o mu wa yẹ lati jẹ́ alabapin ninu ogún awọn eniyan-mímọ́ ninu ìmọ́lẹ̀: (Ef 5:20; 1:11.)

13. Ẹni ti o gbà wá kuro lọwọ agbara okùnkùn, ti o si ṣí wa nipo sinu ijọba ayanfẹ ọmọ rẹ̀: (Ef 6:12; 2 Pet 1:11.)

14. Ninu ẹni ti awa ni idande nipa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, ani ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀:

**Kristi ati iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀.**

15. Ẹni ti o jẹ aworan Ọlọrun ti a kò rí, akọbi gbogbo ẹ̀dá: (2 Kor 4:4; Ifh 3:14.)

16. Nitori ninu rẹ̀ ni a tida ohun gbogbo, ohun ti nbẹ ni ọ̀run, ati ohun ti nbẹ ni ayé, èyi ti a ri, ati eyi ti a kò rí, wọn ìbá ṣe ìtẹ́, tabi ìṣàkóso, tabi ijọba, tabi àṣẹ, nipasẹ rẹ̀ ni a dá ohun gbogbo ati fun un.(Heb 1:2;2:10; Ef 1;20,21.)

17. Oun si wà ṣaaju ohun gbogbo, ati ninu rẹ̀ ni ohun gbogbo duro ṣọkan (Jhn 1:1; 8:58.)

18. Oun si jẹ orí fun ara, eyi sì ni ìjọ: ẹni ti i ṣe ipilẹ̀ṣẹ̀, akọbi lati inu okú wá; pe, ninu ohun gbogbo ki oun lè ni ipo ti o ga julọ. (Ef 1:22,23; Ifh 1:5.)

19. Nitori dídùn inu Baba ni pe ki ẹ̀kún gbogbo lè maa gbe inu rẹ̀; Jhn 1:16.)

20. Ati nipasẹ rẹ̀ lati ba ohun gbogbo làjà, lẹhìn tí o ti fi ẹ̀jẹ̀ agbelebu rẹ̀ pari ìjà; mo ni, nipasẹ rẹ̀, wọn ìbáà ṣe ohun ti nbẹ ni ayé, tabi ohun ti ńbẹ ni ọ̀run. (2 Kor 5:18; Ef 2:13,14.)

21. Ati ẹ̀yin ti o ti jẹ àlejò ati ọ̀tá rí ninu ọkan yin nipa iṣẹ buburu yin, ẹ̀yin

ni o ti bá laja nisinsinyìí, (Rom 5:10; Ef 2,3.)

22. Ninu ara rẹ̀ nipa ikú, lati mu yin wá iwaju rẹ̀ ni mímọ́ ati àìlábà-wọ́n ati àìníbáwí; (Rom 7:4; Ef 2:15; 5:27.)

23. Bi ẹ̀yin ba duro ninu igbagbọ, ti ẹ fẹsẹ̀múlẹ̀ ti ẹ sì duro ṣinṣin ti ẹ ko si yẹsẹ̀ kuro ninu ireti ihinrere ti ẹ̀yin ti gbọ, eyi ti a si waasu rẹ̀ fun gbogbo ẹ̀dá ti nbẹ labẹ ọrun, eyi ti a fi emi Paulu ṣe iranṣẹ fun. (Ef 3:17; Rom 10:18.)

**Iṣẹ iranṣẹ Paulu.**

24. Nisinsinyìí emi nyọ̀ ninu ìyà mi nitori yin, emi si nmú ipọnju Kristi ti o kù pé ninu ara mi, nitori ti ara rẹ̀, ti i ṣe ìjọ.

25. Ninu eyi ti a fi emi ṣe iranṣẹ fún, gẹ́gẹ́ bi iṣẹ ìrijú Ọlọrun ti a fifun mi fun yin lati mu ọ̀rọ̀ Ọlọrun ṣẹ; (Ef 3:2.)

26. Ani ohun ijinlẹ ti o ti farasin lati ayérayé ati lati irandiran, ṣugbọn ti a ti fihàn nisinsinyìí fun awọn eniyan-mímọ́ rẹ̀. (Ef 3:3,4.)

27. Awọn ẹni ti Ọlọrun ni ifẹ sí lati fi hàn fún, kinni titobi rẹ̀ laarin awọn Keferi, ni ọrọ̀ ogo ti ohun ijinlẹ yìí, ti i ṣe Kristi, ireti ogo, ninu yín. (2 Kor 2:14; Rom 9:23; 1 Tim 1:1.)

28. Ẹni ti awa nwaasu rẹ̀ ti a nkilọ̀ fun olukuluku eniyan, ti a si nkọ́ olukuluku eniyan ninu ọgbọ́n gbogbo; ki a lè mu olukuluku eniyan wà ni iwa pípé ninu Kristi Jesu: (Kol 3:16; 1 Kor 2:6,7.)

29. Eyi ti emi nṣe làálàá ti mo si njìjàkadì fún pẹlu, gẹgẹ bi iṣẹ́ agbara rẹ̀ ti o nṣiṣẹ gidigidi ninu mi. (1 Kor 15:10; Kol 2:1; Ef 1:19.)

## ORI 2.

**Aniyan Paulu fun Ijọ Kolosse.**

NITORI emi fẹ́ ki ẹ̀yin mọ̀ bi itara ti mo ni fun yin ti pọ̀ tó, ati fun awọn ara Laodikea, ati fun gbogbo awọn ti kòì tìì ri oju mi nipa ti ara; (Kol 1:29; 4:12.)

2. Ki a lè tu ọkàn wọn ninu, bi a ti so wọ́n pọ̀ ninu ifẹ, lati ni gbogbo ọrọ̀ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ oye ti o dájú, ati ìmọ̀ ohun ijinlẹ Ọlọrun, ti Kristi: (Filp 3:8.)

3. Ninu ẹni ti a ti fi gbogbo iṣura ọgbọ́n ati ti ìmọ̀ pamọ́ sí. (Isa 45:3; Rom 11:33.)

4. Eyi ni mo si nwi, ki ẹnikẹni má baa fi ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn mu yin ṣìnà.

5. Nitori pe bi emi kò tilẹ si lọdọ yin ni ara, ṣugbọn emi nbẹ lọdọ yin ninu ẹmi, mo nyọ̀ mo si nkiyesi ẹ̀tọ́ yin, ati iduroṣinṣin igbagbọ yin ninu Kristi. (1 Tess 2:17; 1 Kor 14:40; 1 Pet 5:9.)

6. Nitori naa, bi ẹ̀yin ti gba Kristi Jesu Oluwa, bẹẹ ni ki ẹ maa rìn ninu rẹ̀: (1 Tess 4:1.)

7. Ki ẹ fi gbòngbò múlẹ̀, ki a si gbe yin ró ninu rẹ̀, ki ẹ si fi ẹsẹ̀ mulẹ ninu igbagbọ yin, gẹ́gẹ́ bi a ti kọ́ yin, ki ẹ si maa pọ̀ ninu rẹ̀ pẹlu idupẹ. (Ef 2:21.)

**Jesu Kristi ni títóbi wà.**

8. Ẹ maa kiyesara ki ẹnikẹni máṣe fi ìmọ̀ ati ẹ̀tàn asán dì yín ni ìgbèkùn gẹgẹ bi ìtàn eniyan gẹgẹ bi ipilẹ̀ṣẹ̀ ẹ̀kọ́ ayé, ti ki i ṣe bi ti Kristi. (1 Kor 8:9; 1 Tim 6:20; Gal 4:3.)

9. Nitori pe ninu rẹ̀ ni gbogbo ẹ̀kún ìwà-Ọlọrun ngbe ninu ara (Jhn 1:14; Kol 1:19.)

10. A si ti ṣe yin ni kíkún ninu rẹ̀, Ẹni ti i ṣe ori fun gbogbo ijọba ati agbára: (Ef 1:21,22.)

11. Ninu ẹni ti a ti fi ìkọlà ti a ko fi ọwọ́ ṣe kọ yin ni ilà, ni bíbọ́ ara ẹ̀ṣẹ̀ silẹ̀, ninu ikọla Kristi. (Rom 2:29; Filp 3:3; Rom 6:6; Gal 5:24.)

12. Bi a ti sin yín pọ̀ pẹlu rẹ̀ ninu baptismu, ninu èyí ti a sì ti jí yin dide pẹlu rẹ̀ nipa igbagbọ ninu iṣẹ Ọlọrun, ẹni ti o ji dide kuro ninu oku. (Rom 6:4,5; A.A. 2:24.)

13. Ati ẹ̀yin, ẹni ti o ti ku nitori ẹ̀ṣẹ̀ yin ati aikọla yin, mo ni ẹ̀yin ẹni ti o si ti sọ di ààyè pọ̀ pẹlu rẹ̀, o si ti dari gbogbo ẹṣẹ̀ yin jì yin; (Ef 2:1.)

14. O si ti pa iwe-akọọlẹ̀ ti o lodi si wa rẹ́ pẹlu ìlànà ofin rẹ̀; eyi ni o si ti mu kuro loju ọna, o si kan an mọ́ agbelebu; (Ef 2:15.)

15. O si ti gba agbara kuro lọ́wọ́ awọn aláṣẹ-ayé ati awọn alagbara, o si ti dójú ti wọn ni gbangba, o nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lori wọn ninu rẹ̀. (Gen 3:15; Isa 53:12; Ef 6:12.)

**Adábọwọ́ ẹ̀sìn ati irubọ ni a ti kọ̀ silẹ.**

16. Nitori naa ẹ má ṣe jẹ ki ẹnikẹni maa ṣe idajọ yin niti jíjẹ, tabi niti mimu, tabi niti ọjọ àsè, tabi oṣù titun, tabi ọjọ isinmi: (Rom 14:3; 14:17; 14:5; Gal 4:10,11.)

17. Awọn ti i ṣe òjìji ohun ti nbọ: ṣugbọn ti Kristi ni ara; (Heb 8:5.)

18. Ẹ má ṣe jẹ ki ẹnikẹni lọ́ èrè yin gbà lọwọ yin nipa mimu yin ṣe irẹ-araẹni-sílẹ̀, ati bíbọ awọn angẹli, ti o si nmu iduro rẹ̀ lori iran ti o nri, ti o si nfẹgẹ̀ àìnídi nipa èrò ti ọkan ara rẹ̀. (Filp 3:14.)

19. Ti ko si di Orí naa mú ṣinṣin, lati ọdọ ẹni ti a nti ipa oríkèé ati iṣan pèsè fun gbogbo ara, ti a si nso o ṣọkan pọ̀, ti o si ndagba nipa ìbísí Ọlọrun. (Ef 1:22.)

20. Bi ẹ̀yin bá ti ku pẹlu Kristi kuro ninu ipilẹ̀ṣẹ̀ ohun ayé, eehatiṣe ti ẹ̀yin tun fi ngbe igbe ayé bi ẹni pe ẹ̀yin sì tún jẹ́ ti ayé? (Rom 6:3,5; Gal 4:3,9.)

21. "Má ṣe fọwọkan, má ṣe tọ́wò, má ṣe fọwọ́bà,"

22. (Gbogbo eyi ti yoo ti ipa lílò run), gẹgẹ bi ilana ti ẹkọ eniyan (1 Kor 6:13; Isa 29:13; Tit 1:14.)

23. Nitootọ́, awọn nkan wọnyìí ní àfarawé ọgbọ́n, ni mimuni ṣe ifaraẹni-jọ́sìn lílelíle, ìrẹ-araẹni-sílẹ̀, ati ipọn-ara-lójú, ṣugbọn awọn wọnyìí kò ni èrè lati dá ifẹkufẹ ara dúró. (Rom 13:14; 1 Tim 4:8.)

## ORI 3.

**Ibi ti ìyè Kristiani tootọ wà.**

NJẸ bi a ba ti ji yin dide pẹlu Kristi, ẹ maa ṣàfẹ́rí awọn nkan ti nbẹ lókè, nibi ti Kristi wà ti o si joko lọwọ ọ̀tún Ọlọrun. (Psm 110:1; Rom 8:34.)

2. Ẹ maa ronu awọn nkan ti nbẹ lókè ki i ṣe awọn nkan ti nbẹ ni ayé. (Filp 3:19,20.)

3. Nitori ẹ̀yin ti kú, a sì fi ìyè yín pamọ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun. (Rom 6:2; 2 Kor 5:14.)

4. Nigba ti Kristi, ẹni ti nṣe ìyè wa, yoo farahan, nigba naa ni ẹyin pẹlu yoo farahan pẹlu rẹ̀ ninu ogo. (1 Jhn 3:2; 14:6.)

**Pa iṣẹ́ ti ara run.**

5. Nitori naa ẹ maa pa ẹya-ara yin ti nbẹ ni ayé run: àgbèrè, iwa-eeri, ifẹkufẹ, ifẹ buburu, ati ojúkòkòrò, ti i ṣe ibọriṣa: (Rom 6:13; Ef 5:3,5.)

6. Nitori nkan wọnyìí ni ibinu Ọlọrun ṣe nbọ̀wá *(sori awọn ọmọ alaigbọran). (Rom 1:18; Ef 5:6.)

7. Ninu eyi ti ẹ̀yin pẹlu ti nrin nigbakan rí, nigba ti ẹ̀yin ti wà ninu nkan wọnyìí. (Ef 2:2.)

8. Ṣugbọn nisinsinyìí, ẹ fi gbogbo wọnyìí silẹ: ibinu, irunu, àránkan, ọ̀rọ̀-ọ̀dì, ati ọ̀rọ̀ ìtìjú kúrò lẹnu yín. (Ef 4:22,29.)

9. Ẹ má si ṣe purọ fun ẹnikeji yin, ẹ̀yin sá ti rii, pe ẹ ti bọ́ ogbologbo ọkunrin nì silẹ pẹlu ìṣe rẹ̀; (Ef 4:25; 4:22.)

10. Ẹ sì ti gbe ọkunrin tuntun ni wọ̀, eyi ti a sọdi tuntun si ìmọ̀ gẹ́gẹ́ bi aworan ẹni ti o da a: (Rom 12:2; Ef 4:23; 2:10.)

11. Nibi ti kò lè si Griki ati Ju, ikọla ati aikọla, alaìgbédè, ara Skitia, ẹrú ati ominira: ṣugbọn Kristi ni ohun gbogbo, ninu ohun gbogbo. (Gal 3:28; Ef 1:23.)

12. Nitori naa bi ayanfẹ Ọlọrun, ẹni mimọ́ ati olufẹ, ẹ gbe ọkàn ìyọnú wọ̀, iṣeun, ìrẹ̀lẹ̀, inú tútù, ipamọra; (Gal 5:22,23; Filp 2:3; 2 Kor 6:6.)

13. Ẹ maa farada a fun ara yin, ẹ si maa dariji ara yín bi ẹnikẹni ba ni ẹ̀sùn si ẹnikan: bi Kristi ti dariji yin, gẹgẹ bẹẹ ni ki ẹyin maa ṣe pẹlu (Ef 4:2,32.)

14. Ati bori gbogbo nkan wọnyìí, ẹ

(6) *(Bibeli atijọ miran fi ẹ̀yí kún ti wọn.)

gbe ifẹ wọ̀, ti i ṣe amure ìwà pípé. (Ef 4:3.)
15. Ẹ si jẹ ki alaafia Ọlọrun maa ṣe àkóso ọkàn yín, eyi ti a pe yin si pẹlu ninu ara kan, ki ẹ si maa dupẹ (Filp 4:7; 1 Kor 7:15; Ef 4:4.)
16. Ẹ jẹ́ ki ọ̀rọ̀ Kristi maa gbe inu yin lọpọlọpọ ninu ọgbọ́n gbogbo; ki ẹ si maa kọ́ ara yin ki ẹ si maa gba ara yin niyanju ninu Psalmu ati orin ìyìn ati orin ẹ̀mí, ẹ maa fi oore-ọfẹ kọrin ni ọkan yin si Oluwa. (Ef 5:19.)
17. Ohunkohun ti ẹ̀yin bá sì nṣe ni ọ̀rọ̀ tabi ni iṣe, ẹ maa ṣe gbogbo wọn ni orukọ Jesu Oluwa, ẹ maa fi ọpẹ́ fun Ọlọrun Baba nipasẹ rẹ̀. (1 Kor 10:31; Ef 5:20.)

**Idile Ọnigbagbọ.**

18. Ẹ̀yin aya, ẹ maa tẹriba fun awọn ọkọ yín, gẹ́gẹ́ bi o ti yẹ ninu Oluwa. (Ef 5:22; 6:9.)
19. Ẹ̀yin ọkọ, ẹ maa fẹran awọn aya yin, ẹ má sì ṣe korò si wọn. (Ef 5:25.)
20. Ẹ̀yin ọmọ, ẹ maa gbọ́ ti awọn obi yin ni ohun gbogbo; nitori èyí dara gidigidi ninu Oluwa. (Ef 6:1.)
21. Ẹ̀yin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ yin binu, ki wọn má baa rẹ̀wẹ̀si, (Ef 6:4.)
22. Ẹ̀yin ọmọ-ọ̀dọ̀, ẹ gbọ́ ti awọn ọ̀gá yin nipa ti ara ninu ohun gbogbo; ki i ṣe ni àrìojúṣe, bi awọn aláṣewù eniyan; ṣugbọn ni otitọ inu, ni ibẹ̀ru Ọlọrun; (Ef 6:5,6; Film 16.)
23. Ohunkohun ti ẹ̀yin ba nṣe, ẹ maa fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, kìí sì í ṣe fun eniyan;
24. Ki ẹ mọ pe lọwọ Oluwa ni ẹ̀yin o gba èrè ogún: nitori ẹ̀yin nsin Oluwa Kristi. (Ef 6:8; 1 Kor 7:22.)
25. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ṣe àìṣòdodo, a o san án fún un nitori àìṣòdodo naa ti o ti ṣe: kò sì sí ojusaju eniyan. (Ef 6:8,9; A.A. 10:34.)

## ORI 4.

ẸYIN ọ̀gá, ẹ maa fi èyí ti o tọ́ ti o si dọ́gba fun awọn ọmọ-ọdọ yin; ki ẹ si mọ pe ẹyin pẹlu ní Ọ̀gá kan ni ọ̀run. (Lef 25:43; Ef 6:9.)

**Diduro ṣinṣin ninu adura.**

2. Ẹ maa duro ṣinṣin ninu adura gbígbà, ki ẹ si maa ṣe ẹ̀ṣọ́ ninu rẹ̀ pẹlu idupẹ; (Rom 12:12; Ef 6:18; Filp 2:7.)
3. Ju gbogbo rẹ̀, ẹ maa gbadura fun wa pẹlu ki Ọlọrun lè ṣí ilẹkun fun wa fun ọ̀rọ̀ naa, lati maa sọ ohun ijinlẹ Kristi, nitori èyí ti mo ṣe wà ninu ìdè pẹlu: (Ef 6:19; 1 Kor 16:9; Ef 6,20.)
4. Ki emi le fihàn, gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati maa sọ,

**Ìhùwàsí.**

5. Ẹ maa rìn nipa ọgbọ́n si awọn ti nbẹ lode, ki ẹ si maa ṣe irapada ìgbà. (Ef 5:15,16.)
6. Ẹ jẹ ki ọ̀rọ̀ yin dapọ mọ́ oore-ọfẹ nigba gbogbo, eyi ti a fi iyọ̀ dùn, ki ẹ̀yin lè mọ̀ bi ẹ̀yin o ti maa da olukuluku eniyan lóhùn: (Ef 4,29; Mk 9:50; 1 Pet 3:15.)

**Paulu sọrọ nipa Tikiku ati Onesimu.**

7. Gbogbo bi nkan ti rí fun mi ni Tikiku yoo jẹ ki ẹ mọ̀; arakunrin olufẹ ati olootọ́ iranṣẹ, ati ẹlẹgbẹ́ wa ninu Oluwa: (Ef 6:21,22.)
8. Ẹni ti mo ti rán si yin nitori eyi kannaa ki ẹ̀yin lè mọ̀ bi a ti wà, ki oun lè tu ọkàn yin ninu;
9. Pẹlu Onesimu, arakunrin olootọ́ ati olufẹ, ẹni ti i ṣe ọ̀kan ninu yin. Awọn ni yoo sọ ohun ti a nṣe nihinyìí fun yin. (Film 10.)

**Ìkíni lati ọdọ awọn ọ̀rẹ́, ati ọ̀rọ̀ Ikẹhin.**

10. Aristarku, ẹlẹgbẹ́ mi ninu tubú ki yin, ati Marku, ọmọ arabinrin Barnaba (nipa ẹni ti ẹ̀yin ti gba àṣẹ: – bi o ba si wá sọ́dọ yin, ẹ gbà a), (A.A. 19:29; 15:37; 4:36.)
11. Ati Jesu, ẹni ti a npè ni Justu, ẹni ti i ṣe ti awọn onílà. Awọn wọnyìí nikan ni olubaṣiṣẹ mi fun ijọba Ọlọrun, awọn ẹni ti o ti jasi ìtùnú fun mi (A.A. 11:2; Rom 16:3.)
12. Epafra, ẹni ti o jẹ ọ̀kan ninu yin, iranṣẹ Kristi, ki yin, oun nfi itara gba-

dura nigba gbogbo fun yin, ki ẹyin lè duro ni pípé ati ni kíkún ninu gbogbo ifẹ Ọlọrun. (Kol 1:7; Rom 15:30; Filp 3:15.)
13. Nitori mo jẹri rẹ̀ pe, o ni itara pupọ fun yin, ati fun awọn ti o wà ni Laodikea; ati awọn ti o wà ni Hierapoli. (Kol 2:1.)
14. Luku, onişegun olufẹ, ati Dema ki yin. (2 Tim 4:10,11; Film 24.)
15. Ẹ ki awọn ará ti o wa ni Laodikea, ati Nimfa, ati ìjọ ti o wà ni ile rẹ̀. (Rom 16:5.)
16. Nigba ti a ba sì ka iwe yìí laarin yin tán, ki ẹ mu ki a kaa ninu ìjọ Laodikea; ki ẹ̀yin pẹlu si ka èyí ti o ti Laodikea wá.
17. Ki ẹ si wi fun Arkippu pe, "Kiyesi işẹ Iranşẹ ti iwọ gba ninu Oluwa, ki o sì şe é ni kikún." (Film 2; 2 Tim 4:5.)
18. Ìkínni nipa ọwọ́ emi Paulu. Ẹ maa ranti ìdè mi. Ki oore-ọfẹ wà pẹlu yin. (Amin.) (1 Kor 16:21; Heb 13:3; 13:25.)

52

# AWỌN ARÁ TESSALONIKA KINNI

**(A.D. 54)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, sí ijọ awọn ara Tessalonika, ninu Ọlọrun Baba, ati ninu Jesu Kristi Oluwa: Oore-ọ̀fẹ́ si yin, ati alaafia. (2 Tess 1:1; 2 Kor 1:19; A.A. 16:1; 17:1; Rom 1:7.)

**Paulu ndupẹ fun gbogbo wọn lọwọ Ọlọrun.**

2. Awa dupẹ lọwọ Ọlọrun nigba gbogbo fun gbogbo yin, awa nşe iranti yin ninu adura wa; (2 Tess 1:3; Rom 1:8,9.)
3. Ni àìsinmi ni awa nranti işẹ́ igbagbọ yin ati làálàá ìfẹ́ ati suuru ìrètí yin ninu Oluwa wa Jesu Kristi, niwaju Ọlọrun ati Baba wa; (2 Tess 1:11; 1:3.)
4. Nitori pé awa mọ yíyàn yin, ará, olufẹ ti Ọlọrun;
5. Nitori ihinrere wa kò wá sọdọ yin ni ọ̀rọ̀ nikan, şugbọn ni agbara pẹlu, ati ninu Ẹmi Mimọ, ati ni ọpọlọpọ igbẹkẹle; bi ẹ̀yin ti mọ iru eniyan ti awa jẹ laarin yin nitori yin. (2 Tess 2:14; Kol 2:2; 2 Tess 3:7.)
6. Ẹ̀yin sì di aláfarawé wa, ati ti Oluwa, bi o tilẹ jẹ ninu ipọnju pupọ ni ẹyin fi gba ọ̀rọ̀ naa, pẹlu ayọ̀ ti Ẹmi-Mímọ́; (1Kor 4:16;11:1;A.A.13:52.)
7. Ti ẹ̀yin si jẹ́ apẹẹrẹ fun gbogbo awọn ti o gbagbọ ni Makedonia ati Akaia.
8. Nitori lati ọdọ yin lọ ni ọ̀rọ̀ Oluwa ti dún jade, ki i şe ni kìkì Makedonia ati Akaia nikan, şugbọn ni ibi gbogbo ni ìhìn igbagbọ yin si Ọlọrun tàn kálẹ̀; tobẹẹ ti awa kò ní ohunkohun lati tún sọ mọ́. (Rom 10:18; 1:8; 2 Tess 1:4.)
9. Nitori pe awọn tikarawọn rohìn nipa wa, iru igbanisọ́dọ̀ ti a ni laarin yin, bi ẹ̀yin sì ti yipada si Ọlọrun kuro ninu ère lati maa sin Ọlọrun alààyè ati otitọ; (1 Kor 12:2; Gal 4:8.)
10. Ati lati duro de Ọmọ rẹ̀ lati ọrun wá, ẹni ti o sì jí dide kuro ninu òkú, ani Jesu naa, ẹni tí o gbà wá kuro ninu ibinu ti nbọ. (2 Pet 3:12; A.A. 2:24; Rom 5:9.)

ORI 2.

**Işẹ́ Paulu laarin awọn eniyan.**

NITORI ẹ̀yin tikarayin mọ̀, ará, irú ìbẹ̀wò wa si yin pé ki i şe lásán; (1 Tess 1:5,9.)